# IROHIN IMOLẸ

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

No 1, 474, TUESDAY OCTOBER 5 1965 (2D)


## Awon Odo Wa Lẹhin Adegbenro

IBADAN:— Niau irohin kan to de ile iṣẹ wa lati ọwọ ẹgbẹ ọdọ ẹgbẹ itẹsiwaju eyiti nwọn npe ni "UPGA Youth Front" ni awọn ẹgbẹ odọ na ti ṣe alaye pe awọn gba wipe ki nwon ṣe ofin pajawiri si Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ju pe ki nwon jẹki ẹgbẹ Dẹmọ tun fi ọgbọn eru bori ibo si Ile Igbimọ Aṣofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria to mbọ yi.

Awọn omo ẹgbẹ ọdọ na sọ eyi ninigbati awon ba awọn Oniwe Irohin ṣe ipade ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kerin lelogun oṣu to kọja ni ilu Ibadan.

Awọn ọmọ ẹgbẹ na sọ pe awon wa lẹhin Adele Aṣiwaju ẹgbẹ Afẹnifẹre Alhaji Dauda Soroye Adegbenro lori oro ti o so pe on faramo ofin Ijoba Ipinlẹ na ṣe pe ko gbodo si ipade ati iwọde gbangba ode kakiri Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Awon ẹgbẹ ọdọ na tun ṣe alaye pe lẹhin ti Ijọba ṣe ofin na tan ni awọn bere ipolowo ibo lati ile kan si ile keji ati pe awon janduku ẹgbẹ Dẹmọ ko tuo fun won laye.

Awon ẹgbẹ odo UPGA na tun ṣe alaye pe opolopo ile lo jẹ wipe awon ẹgbẹ ọdọ na ma nde lati ṣe ipolowo ibo abele eyiti o jẹ wipe awọn janduku ẹgbẹ Dẹmọ ko ni fun wọn laye lati ṣe ipolowo ibo na eyiti o jẹ pe awọn yio fi iya ma jẹ awọn ọmọ ẹgbẹ wọn.

Awọn ẹgbẹ ọdọ UPGA na tun ṣe alaye pe ọpọlọpọ ọgbọn lo jẹ wipe o kun inu awọn ẹgbẹ Dẹmọ lati ṣe lasiko idibo si ile Igbimọ Asofin Ijọba Ipinlẹ

WO OJU EWE KẸFA

# DOKITA OKPARA YIO LỌ SI IPINLẸ IWỌ ORUN

EKO:— Gbogbo ile lo kunṣọṣọ ti ẹsẹ ko si gbeji fun ogunlọgọ ọkẹaimoye awọn enia ti nwọn wa pade Dokita Michael Okpara, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ila Orun Naijiria ati Olori ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) nigbati o de si ibudo'kọ Ofurufu ni dede agogo mẹjọ ana ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu yi, ti Dokita na si sọ fun gbogbo awọn enia ti nwọn wa pade rẹ ni oju ọna wipe, on pẹlu gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ on ti ṣetan nisisiyi lati lọ si Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria tun ibo ti awọn enia ipinlẹ na yio di ni ọsẹ ti nbọ yi.

Ṣugbọn nigbati awọn Oniwe Irohin bi Dokita Okpara lere boya o fẹ sọ ohun kan nigbati ọkọ rẹ gunlẹ si Ikẹja, Ṣugbọn Dokita Okpara da awọn Oniwe Irohin lohun wipe, on ko ni ṣọrọ kankan fun wọn ni Eko.

Dọkita Okpara tun sọ si waju ninu ọrọ rẹ wipe gbogbo ohunti on yio ba sọ nipa ọrọ ibo ti nbọ yi ni Ipinlẹ Iwọ Orun, o di igba ti o ba de Ogbomọshọ ti iṣe ilu Oloye Akintọla, nigbana ni on yio to sọrọ ti o yio ba sọ.

Dọkita Okpara tun sọ pẹlu wipe, nigbati on ba de Ogbomọshọ, nibẹ ni gbẹgẹdẹ yio gbe lọ gbina, ṣugbọn o rọ gbogbo awọn Oniwe Irohin ti nwọn ba fẹ mọ ohunti yio ṣẹlẹ ki nwọn ma jafara ki nwọn kalọ, ki nwọn si lọ fi oju arawọn ri ohunti yio ba ṣẹlẹ ni Ogbomọshọ.

Nigbati Oniwe Irohin kan bere wipe "Kini ero ọkan rẹ nipa Irohin ti o jade wipe, Oloye Akintọla wọle, laisi alatako"

Dọkita Okpara sọ wipe, "Ẹru lo nba Oloye Akintọla, nitoripe, o ti mọ daju daju wipe, awọn enia Ipinlẹ Iwọ Orun ko fẹran ẹgbẹ Dẹmọ, nitorina, ni Oloye Akintọla ṣe nwa ọna ki on maṣe le de ọdọ awọn enia na, ko si fẹ ki nwọn dibo pẹlu nitori iberu yi."

"Oloye Akintọla ti mo wipe, awon enia Ipinlẹ Iwọ Orun ko ni ifẹ si ẹgbẹ Dẹmọ o si tun ti ipa j'oba le awon enia na l'ori bi nwon fẹ bi nwon ko, nitorina, ẹru nba Oloye Akintola lati de ọdo awon enia rẹ, wipe ki nwon dibo fun ẹgbẹ on ninu ibo yi"

Dokita Okpara pẹlu gbogbo awon omo ẹgbẹ rẹ ni nwon ṣe ipade ni alẹ ana ti nwon si ti pari gbogbo eto ti nwon fẹ ṣe, nipa lilo ti nwon nlo si Ipinlẹ Iwo Orun,

A gbo wipe, awon enia na yio lo si Iwo Orun l'oni, Ogbomosho ni nwon yio si koko lo, nibẹ ni Dokita Okpara yio gbe ba awon enia soro.

Awon alaṣẹ Iwe Irohin Imolẹ ti ṣe eto wipe, ki Oniwe Irohin wa kan ba Dokita Okpara lo si Ogbomosho, bi irinajo na ba si tiṣe ri, ẹ o maa gbo.



Aworan oke yi ni ti Dokita Okpara nigbati o ba ọkọ ofurufu de si Ikeja ni alẹ ana pẹlu Oloye Dennis Osadebay.

# Iwe si Olotu Irohin Imọlẹ

## Awa Ko Fẹ Woli Eke

Olotu, Jọwọ gba mi laye rampẹ lati fi ẹdun ọkan mi han lori Ọgbẹni lasanlasan kan ti o ma nṣọrọ sinu iwe rẹ ti o pe ara rẹ ni "PASTOR OLU".

Bi enia ba jẹ ojiṣẹ Ọlọrun ko dara ki o tun ma lọwọ ninu ọrọ Oṣelu, bi enia ba si nwasu lori iwa ibajẹ ti awọn ọmọ araiye hu ko dara ko tun ma sọrọ lori ọrọ Oṣelu, nitori ti enia ko le ko irin-meji bọra lẹkanṣoṣo.

Nigbati Woli nwasu, ti o si tun nsọrọ Oṣelu ewo ni o yẹ ki a gbọ nitorina Olotu ẹ ba wa kilọ fun Woli eke yi o, Bibeli Mimọ paapa sọ wipe Ẹ fi ohun ti Kesari fun Kesari, ki ẹ si fi ohun ti Ọlọrun fun Ọlọrun.

Ẹ si tun ba wa kilọ fun Pastor Olu ki o ye ma bu ẹnu atẹ lu ayanfẹ awọn ọmọ Oduduwa ti o ba nwasu rẹ, nitoripe ẹnikan ṣe nijọsi Iyemoja lo gbe lọ.

Emi ni
Adebiyi Falodun
Oshogbo

gba mi ni aye diẹ ninu iwe rẹ alakagbadun lati kesi gbogbo awọn adibo Ipinlẹ Iwọ Orun pe ki nwọn o jọwọ jẹki a fi tọkantọkan dibo fun ẹgbẹ Ọlọpẹ ati Alakukọ.

Awọn idi pataki ni o wa ti a fi ni lati dibo fun ẹgbẹ Ọlọpẹ nipe lati igbati ẹgbẹ Dẹmọ ti wa lori akoso Ijọba ko si alafia ni ilu, ilokulo si ni awọn ẹgbẹ na si nlo owo awa Agbẹ bakanna ni nwọn si nlo ofin buruku lori awa mẹkunnu.

Ọgọrọ enia ni Ijọba Dẹmọ ti ju sẹwọn nitori owo-ori ati laiko ṣe, gbogbo Ipinlẹ wa ni awọn ẹgbẹ na ti bajẹ nitori idi eyi ẹ jẹki a kọ ẹgbẹ Dẹmọ ki a si dibo fun ẹgbẹ UPGA.

Olotu mo dupẹ aye ti ẹ gba mi Oluwa yio wa pẹlu yin o

Emi ni
Yinka Adejuwon
SHAKI

## Ibarapa Ẹ Maṣe Dibo Fun Dẹmọ

Olotu, Jọwọ gba mi laye ranpẹ yi ninu iwe rẹ Irohin Imọlẹ lati ke si gbogbo awọn ọmọ ilu Ibarapa lori ibo ipinlẹ Iwọ Orun ti abọ yi.

Mo bẹ ẹnyin Ibarapa, ẹ maṣe dibo fun ẹgbẹ Dẹmọ, ko si ore kan ti ẹgbẹ na ṣe fun Ibarapa lati igbati nwọn ti wa lori akoso Ijọba, nitorina ẹ maṣe dibo fun won o, mo fi alalẹ Ibarapa bẹ nyin, UPGA ni ki ẹ dibo fun eyiti nṣe ajumọṣepọ ẹgbẹ Ọlọpẹ ati Alakukọ

Nitori ni asiko ti Awolọwọ wa ni ile, o ṣe ọpọlọpọ ore fun ilu wa papa ile iwe ọfẹ ti o da silẹ fun awọn ọmọ wa bi a ba si tun dibo fun ẹgbẹ na wọle, gbogbo nkan ti a nfẹ ni yio tẹwa lọwọ o.

Emi ni
Layiwole Ọlakunle
Eruwa

## Igbo-Ọra, O Di Owo Nyin O !

Mba sọpẹ pupọ pupọ bi Alagba ba le gba mi ni aye diẹ ninu iwe Irohin Imọlẹ rẹ olokiki lati ba awọn ọmọ ilu mi sọrọ nipa ibo Ipinlẹ Iwọ Orun ti a o di ni ojo kokanla osu ti a wa yi

Ẹnyin ara Igbo-Ọra nile loko mo kesi yin loni, ẹ jọwọ ẹ jẹki a fi tọkantọkan dibo fun gbogbo Asojuẹgbẹ Itẹsiwaju UPGA ti nwọn yan silẹ paapa Ọgbẹni Bọlanle Ọlanipan ki a si ko Asoju ẹgbẹ Dẹmọ

Nitori ẹgbẹ a fi oru rin ni ẹgbẹ Dẹmọ nṣe ẹgbẹ Dẹmọ ko si nwa fun enia ẹyin na ẹ wo iru iya ti wọn fi njẹ awọn ọmọ wa lati ọjọ ti nwon ti wa lori aga Ijoba

Lakotan mo fi Oluwa bẹ nyin bi ẹ ba nfẹ ki gbogbo awon nkan idagbasoke ti o wa ni ilu Ibadan na o de Igbo Ọra sti opolopo ile ẹko giga fun awon ọmọ wa ẹgbẹ itẹsiwaju ni ki ẹ jẹki a dibo wa fun o

ẹ maṣe jẹki a gbagbe olote, nitori olote wa ni Oloye Ọbafẹmi Awolowo ẹ jẹki a fi ibo wa da Awo late, Ẹ dibo fun opẹ ati Akuko ki idẹra ati alafia le pada bo si Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Emi ni
L. A. T Akintunde
IGBO ỌRA

## Akomolafẹ, E Ku Iṣẹ O!

Olotu, ọmọ ori Ade, jọwọ ma ṣe alai ko fun mi ni aye ranpẹ yi ninu iwe rẹ olokiki ti o njẹ Irohin-Imọlẹ lati ki ẹgbẹ Okanle—Islamic Centre pẹlu Alaga ẹgbẹ na fun iṣẹ ola ula ti nwọn nṣe silu Okanle fun idagbasoke ẹsin Islam Mo ki Ọgbẹni S A Akomọlafẹ ti nṣe a aga ẹgbẹna ati gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ na fun iṣẹ ribiribi tiwọn ṣe ati fun ile kewu ola ti nwọn kọ fun awọn ọmọ wa Oluwa yio ma ran won lọwọ.

Ṣugbọn on kan ti o tun ku ti mo fẹ ki awọn ẹgbẹ na ṣe ni pe ki won o kọ ile-iwe kekereati giga ti yio jẹ ti Musulumi ti wọn o ma kọ awọn ọmọ ni kewu pẹlu iwe bi ti Ijọ Ahmadiyya ati ti Ansarudeen l'Eko.

Mo si lero pe awọn ẹgbẹ na yio gba imọran mi yi nwọn o si sa agbara lati ṣe bẹ Oluwa yio ran yin lọwọ o.

Emi ni
Afinurode Ilu
Okanle—Igbomina

## Ẹ Dibo Fun Ọpẹ

Dakun Alagba, ẹ maṣe alaiko


## APIAS RHUMATIC & DRAGEES

Jẹ ojulowo hauhaun egbogi Jamoni to lagbara gidigidi fun iwosan "LAKUREGBE" to mba enia ja

Orișiriși lakuregbe ni o wa Lakuregbe Arungun ti o ma nsan enia ninu egungun ara lakuregbe tio ma nwu enia ni ẹsẹ roboto tio njẹki ẹsẹ wuwo la i ma bikina Lakuregbe tio ngbe ori erike dinwo kori bi o ti rọ ran lati lo tabi ki o ma ṣe ayipada ẹsẹ, ara tita bi eyiti enia fi ata obẹ pa ibadi tabi egusi ara wiwo, ako iba tabi pon tabi rirun.

Bi enia ko ba gba jumọ lati foju rẹ lasiko ole so owo pa rẹ lasiko



WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palmchurch Street Lagos
NIGERIAN MEDICINE STORES
4 Tinubu Square Lagos



## Bọ Lọwọ Ọṣọ Ati Ajẹ

Iwe egbogi Ajẹbidan 25/- meji £2
Iwe Ilana Ifa Iyanrin tiẹ ati etutu rẹ pẹlu Iwosan 20/- mejili £2
Iwe Egbogi Awogba Arun meji 40/-
Turari isẹgun Ajẹ Oṣo ati awọn abanijẹ O wa fun itaja pẹlu alakata Pangolo 10/- Pakẹti 2/- Ki iṣe ti ẹnu fifọn bi o ra ninu awọn oja yi aabo ti o ni ipon yio wa lori rẹ ati awọn ẹbi rẹ.

Fi owo ranṣẹ si

J O SHOYINKA
5 Alaba Sreet,
Ojo abẹyẹ Mushin



it beats...
as it sweeps...
as it cleans...



The NEW de luxe
HOOVER cleaner
Buy yours NOW at:
LEVENTIS TECHNICAL
New showrooms at Iddo, Marina & Mainland Stores, Kingsway, P.Z., U.T.C. Stores and also throughout our branches in Nigeria.

# Ọmọ Itirẹ Eti Nyin Melo ?

**Lati Ọwo M. A. HAMED**
Akọwe Ẹgbe Ọdọ Afẹnifẹre

Ẹnyin ọmọ ilu itirẹ mo fẹ ki ẹ sun ki ẹ lọ ronu nyin jinlẹ nipa ti eto idibo si Ile Igbimọ Aṣofin ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria to mbọ yi ati pe ki ẹ si mọ iru ẹgbẹ to tọ ti o si yẹ lati dibo nyin fun ni ọjọ idibo to ku si dẹdẹdẹ yi ati pe ki ẹ si tun fi imọ nyin ṣọkan.

Ki nto ma ba eto ọrọ mi lọ mo si dupẹ lọwọ Ọgbẹni Wahabi nipa ọrọ rẹ ti oju ewe karun ti iwe Irohin Imọlẹ Owurọ ti ọjọ kejidin logun si ọjọ kẹrinlelogun Oṣu yi nipa ti Ọmọ Ọba Ade-Ojo Ibadan. Ha! kẹke pamọ awọn jẹunjẹun lẹnu awọn ti o titori okele onjẹ ja ija ajatuka ni ọjọ Abamẹta ti iṣẹ ọjọ kejidinlogun osu yi nigbati asia ẹgbẹ Afẹnifẹre mẹfẹfa nfẹ lẹlẹ.

Ogbẹni Wahabi si kan saara si ẹgbẹ Afẹnifẹre o si tun sọ pe iyawo ti a ba yo fẹ iran ni yio si gba lọwọ ẹni eleyi si ni ti ẹgbe Dẹmọnu

Mo fẹ ki ẹ lọ mọ daju pe gbogbo eto ibo yi di ọwọ nyin ati pe ki olukuluku lọ mura gidigidi nipa ti idibo na Mo tun fẹ ki gbogbo ẹnyin enia Itirẹ lọ mọ pe kekere ni abẹrẹ ke te ki iṣe mimi fun adiẹ

Bi o ti wu ki ilu ẹni kere to, ilu ẹni ni ilu ẹni o?e wo ni ipa ṣe fun idi mo si tun bẹ nyin lọmọde ati la gba ki ẹ si fi oju iru wo iru anfani ti o jẹ pe ẹgbẹ Dẹmọnu ṣe si ilu Itirẹ yi tabi fun ti iwe ti nwọn ma a nlẹ mọ ile nyin ti nwọn yio sọ pe Ijọba fẹ lo ilẹ ti ẹ ti fi ọpọlọpọ ọdun kọ ile si

Eleyi ki iṣe pe a npolo wo ibo fun nyin ṣugbọn emi fẹ ki ẹ mọ pe ẹgbẹ Dẹmonu ti sọ nyin di ọgba Ajara ti a ki i toju rẹ ṣugbọn ki a ma ka eso rẹ lọ dọdun ni, Oluwa yio sọ nyin di ọgba ajara otitọ

Emi mo daju pe ko si enia mẹwa ni ilu Itirẹ ti awọn le pa ara won ni ẹgbẹ Dẹmo ti ẹ ba ri iru awon enia bẹ nwon lo jẹun nibẹ ni

Emi si ni idaniloju pe ko si ẹgbẹ Dẹmọ kankan ni ilu Itẹrẹ, ti ẹ ba ri wọn bẹ eleyi si jẹ iru aṣa orin ti nwọn nko pe: 'Bi o ri owo mi bi o ko rinu mi Dẹmo ni mo wa eleyi si ni nwon fi eleyi nṣe,

Mo fẹ ki ẹ lo mo daju pe nkan ti aba ri fun ki iṣe di do bi o ikoko ti o gbe wu Agutan wọ Domonu ko ni da nyin nu ni orina ẹ dibo fun ẹgbẹ itesiwaju (UPGA) eyiti iṣe ẹgbẹ ajumoṣepo ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Alukuko

## Kere o ! Kere o !! Akiyesi Pataki




Awa na le jeri wipe ojulowo hauhau egbogi gidi ni LEOPILLS awa na nlo ni Gold Coast Akkara Ghana pẹlu meji rẹ ko si ninu orisirisi Egbogi kakiri ilu Naijiria.

Bẹ na ni ẹwẹ ni Igboro ilu Eko Irohin ti o wa lẹnu gbogbo enia tọmọde tagba ni as ko yi ti nwọn fi se ọro ati orin larin ara wọn ni nipa Egbogi Jamani olokiki yi ti nwon npe ni LEOPILLS.

Imoran awon Dokita Oyinbo ti nwọn nse iwadi Egbogi LEOPILLS, yi kan sọ wipe bi o ti lagbara to ati o jẹ ojulowo g'riki ati ara matase fun "JẸDIJẸDI" bi o ti wo ki ọjọ re ti pẹ to bẹna ni nwọn ti tun fi owọ sọya tabi ṣe ileri fun gbogbo awọn ti amodi tabi iju, tabi Igbẹ sise, tabi aiko ri igbọnsẹ dede. Inudrun nigbakugba ara wiwo. Esari, ẹhin didun ṣisan, abi aiko ririn kedere ko dawo buruku lara, aisan Onigba meji ati orisirisi arun miran gbogbo pẹlu.

"Wipe nwon yio ri alafia ni kiakia ti nwọn ba nlo egbogi LEOPILLS nitoripe o tun ma tun ẹjẹ ṣe lara enia ni ala siso di otun

RANTI PE ALAFIA LOGUN ỌRỌ IJAFARA SI LEWU PẸLU.

IYE OWO EGBOGI LEOPILLS.– Igo nla sile meje abọ (7/6) pere Igo kekere sile mẹrin (4/) pere. Bere Ojulowo Egbogi miran fun orisirisi Amodi ti ẹ nba fẹ ni Ṣọbu awọn:-

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street Lagos
Phone 22878 (Ọja Ita Faji)
ATI NI ṢOBU
ṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE BOLA IBADAN.

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 20 - Feb 18) Ohunkohun ti o ba dawọle ni sise larin ọsẹ yi, rere ni yio jasi,

PISCES (Feb 19 - Mar 20) Maṣe ba ẹnikẹni da owo pọ larin ọsẹ yi ki o ma ba ri alagbeda.

ARIES (Mar 21 – April 19) Maṣe fi ohunkohun ti o la ni lati ṣe falẹ larin ọsẹ yi ki ọwọ rẹ le tẹ ohun ti o nfẹ

TAURUS (April 20 – May 20) Jawọ kuro ninu ikanra ninu ọse yi ki ire ti o nwa ma ba fo ọ tabi kọja rẹ.

GEMINI May 21 – June 20 Ṣọra pẹlu ọja tita ati rira larin ọsẹ yi ki o ma ba padanu owo

CANCER June 21 July 20 Ṣọra ose yi ko o dara fun ọ lati wọ moto tabi ọkọ omi, ki o ma ba ṣe ofo ẹmi rẹ

LEO July 20 Aug 22 Gbiyanju lati sunmọ awọn enia pataki, lọdọ wọn ni ire wa fun ọ ninu ọsẹ yi

LIBRA Aug 23 Sept 22 Idamu ilẹ yio wa fun ọ larin ọsẹ yi maṣe miran, ayọrisi rẹ rere ni yio jasi fun ọ

VIRGO (Sept 23-Oct 22) Ṣọra pẹlu ọrọ ẹnu rẹ ninu ọsẹ yi ki o ma ba ṣe fi ẹnu dara

SCOKIO (Sept 23 Nov 22) Maṣe fi wuduwudu jaiye ki o ma ba jin si ofun omọ araiye larin ọṣe yi

SAGITTARIUS Nov 22 Dec 21 Ọsẹ ayọ na de ma ṣe bẹru lati dawọle ohunkohun ti o ba ni ifẹ si lati ṣe akiyesi rere ni gbogbo re yio jasi

CAPRICORN Dec 22 Jan 19 Tẹr mọ ohunkohun ti ọwọ rẹ ba ba ni sise larin ọsẹ yi nitoripe nibẹ ni ire wa

## A Tun Gbe De !

Iwe itan igbesi aiye Oduduwa ati ti awọn ọmọ rẹ Iwe yi kun fun itan iṣẹdalẹ. Kedere ni Aworan Oduduwa ati awọn ọmọ rẹ han ninu rẹ. Maṣe jẹki owon o rohin rẹ fun ọ Sile meta 3/- pere ni a ntaa, Postage 9d,

Kọwe Fun Dọsinni rẹ:—

Tete fi owo tirẹ ranṣẹ si

ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
8, Idumagbo Avenue, Lagos Nigeria
(Leti Ọja Janraka l'EKO

# IFI ERU GBIRE LARIN ILẸ WA

**Lode aiye wa loni gbogbo enia mọ duju pe ohun kan pataki yingin pupọ ju igba aiye awọn baba wa to ti kọja lọ si ile a'yeraiye. Bi gbogbo wa ti nsọ pe aiṣotọ wa larin wa bẹni awa ko gbiyanju lati mu iwa na kuro patapata.**

Ọrọ Ọlọrun sọ pe ẹniti o ba mọ rere iṣe ti ko ba ṣe e ẹṣẹ ni fun u. Nitori bi epo pupa ti ri lara aṣọ fun fun bẹni ami ẹṣẹ ri l a r a igbesi aiye ọmọ enia.

Laipẹ yi nigbati a w ọ n Oyinbo wa larin wa gẹgẹbi alaṣẹ ati olutọ wa. Iwa eeru ko pọ to bi o ti wa loni yi. Gbogbo wa ni nmo kun larin ibajẹ bi ẹni mo-kun ninu omi.

Loni ẹrọ gbohun gbohun ati larin ita gbangba ni a ngbọn ti a si nri awọn iwa ti ko yẹ lati ma hu ti awọn enia ima hu bi ẹ n i pe Ọlọrun ko ri nwọn.

Bi o ba le tan mi ṣugbọn iwọ ko le tan ỌBA Ọrun. Larin awon pupo n i n u oṣelu wa ti a ba wo iwa ti wọn nhu a fẹrẹ pa o w ọ lere fọn ẹkun ati ifi ẹṣẹ jẹn ilẹ pẹpẹ. Awọn miran tiẹ gba pe laiṣe pe i ṣ ẹ awon ẹlomiran ba bajẹ aye ko ni st fun won lati lo siwaju Iwa iqi ni eyi ati ibajẹ pẹlu.

Ohun pataki ti o wa lo kan mi lori ọrọ yi loni ni idibo ti o wa ni waju wa loni Pataki ni iha Iwọ Orun Kini ṣe ti a nwa ọna lati pa ẹda bi euwrẹ kuro lori ilẹ alaye? Kini adun idibo lẹhin ibori tabi ao le bori ninu ila kaka idibo? Kini ṣe ti awọn alagbara ko ni ifi ọkan balẹ lori idi ba yi?

Idahun mi lori awọn ibe re wọnyi ni pe, Ibiti aini ifaiyabalẹ ba wa, ibiti a ba nwa ọna lati fi opin si igbe si aiye ọmọ enia ibiti ko ba si adun pipe ti igbesi ati ipahinkeke ba wa lẹhin idibo

Ki a mọ daju pe aiṣe ododo wa ninu ọrọ ta Ọro Ọlorun sọ pe ododo ni ngbe orilẹ ede leke Nitorina ibiti aiṣe ododo ba wa ọna ni ko ṣe fun ire enia bikoṣe iwa ibajẹ

O yẹ ki a mọ daju pe ni nu gbogbo itan aiye ako ri ka pe ijọba kan tabi ẹgbẹ oṣelu kansoso lo wa lori ijọba siṣe Tio ba jọ bẹ ki nide ti awọn oṣelu wa ko fi yedenu lori ọrọ eto ilu ọrọ eto ilu siṣe ko lọna ti awọn opo ninu awon aṣaju wa ẹgba ṣe eto na

Ti a ba wo iha Iwọ—Orun loni ao riawọn iwa miran ti ko ba eti m rara

Awọn miran bi oniṣegun tabi lọya ni a nba mọ ile tubu bi ẹni ha ẹran osin mọ ile

Iru iwa yi ko tọ rara. Nitotọ ika to ba ṣẹ ni oba nke Ṣugbon tia bake awon ika ti yo ba wulo fun ni lẹ hin ola bawo ni ao titun ri ika na lo fun ire ẹnil ẹhin ola

### Bati Ọwo



### S. O. Jaiye

Nitori enitijo ba fun ebu ika ika ara rẹ ni o gbin Emi ko mọ bi awon oṣelu wa ti ma ronu won ni'ori ẹnikẹni ti a ba ha mo ile tubu loni

Daju daju ẹni na ko le gbagbe titi aiye rẹ Nitori ile tubu ki ṣe ile idẹra tabi igbadun rara

Awọn tia yan bi alabaju to idibo ti nkan nfi ibi aye iṣe wọn silẹ lati ma sapa mo kiri gẹgẹbi ati ngbọ Iru iwa bẹ ko dara rara

Njẹ nwọn ko mọ pe wọn nfi aye silẹ fun ẹni buburu lati gaba lori ẹni rere ni? Nitori bi enia meji ba ndu aye kan fi ẹo fun ẹnikan laye ti ẹ ko fun alapakeji laye fun idijẹ ti rẹ ọna eeru ni eyi ati ibajẹ aiye

Paya gidi ti ako ba dẹ hin ninu iwa buburu wọn yi esan to daju nbọ wa ke lori oluṣe buburu gbogbo. Enia ko le gbin ẹfọ ko ma ja ewuro,

Ibi gbogbo ti enia ba ṣe yo jẹhin rẹ ninu ara iyara yi. Fun idi eyi mo rọ gbo gbo awọn oṣelu wa ki wọn lo yẹ wa wọn wo d da Ni tori iṣe ni saju ẹkun aba mọ ni igbẹhin ọrọ

Gbogbo ilu pejọ ṣugbọn nwọn kori ẹbọ abamọ ṣe. Odi ọwo ẹnyin a fi ẹru gbaire lọwọ awọn ẹlomiran

O di gba diẹ

# Ẹgbẹ UPGA

## Lati Oju Ewe Keji

Ko ti i ṣi ọrọ kankan to jẹ wipe o jade lati ẹnu awọn Igbimọ Alakoso eto ibo na lati igbati asiko ti awọn yio fi fi orukọ silẹ na pari ni deede agogo kan ọsan ọjọ Aje tiiṣe ọjọ kẹtadinlọgbọn oṣu yi ati pe awon Igbimọ na ko si tun sọ nkankan nipa awọn ọmọ ẹgbẹ UP—GA ti ko ri awọn Akọwe ibo lati fi orukọ wọn silẹ.

Ninu ọrọ ti Alaga Igbi—mọ eto ibo na sọ lẹhniti nwọn pari fifi orukọ awọn ẹniti awọn enia yio dibo fun ni o ti ṣe alaye pe ọpọ-lọpọ ninu awọn Akọwe ibo lo jẹ wipe nwọn lo ji pamọ ti ko si se iṣẹ fun awọn ọmọ ẹgbẹ Oṣelu ti nwọn fi oruko wọn sile lati ri awon Akowe eto ibo na.

Ṣugbon o ṣe iṣe ki awọn Igbimo eto ibo na fun asi-ko ti nwọn yio fi orukọ silẹ na siwaju diẹ lati le jẹki awon enia ti ko ri ti awon Akowe lati fi oruko won si le fi oruko silẹ ki o to di pe nwon tun pari eto fifi oruko silẹ na.

BERE EGBOGI ARỌ N

**"VERMIZYN"**



Ojulowo egbogi atamatase ti o daju fun iparun awọn ARỌN' Buruku gbogbo lara enia papa tabi ni pataki ARỌN latọnlatọn tabi arọn kinisa ti o ma mu id iwọ wa fun obinrin lati loyun tabi ti o ma nba oyun na jẹ lara Obinrin.

Bẹ si ni egbogi yi dara fun gbogbo ẹniti aran agbẹdu igba aiya, ọna ọfun, sisẹ lẹhin bi ake tabi aran oiu pẹlu Meji iru fẹ egbogi arọn yi kosi ni gbogbo ilẹ Naijiria isẹ rẹ si daju.

AKIYESI PATAKI

Ri daju wipe o ti re eekọnọ ọwọ ati ẹsẹ rẹ daradara ki oto lo egbogi aran yi gẹgẹbi awọn Jaman ti o ṣe ti juwe lilo rẹ Fun agbalagba nikọn ni o wa fun. Bere orisirisi egbogi arọn fun ọmọde pẹlu wọn nbẹ fun tita ni ṣọbu: Naijiria bere ni:-

WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palm Church Street Lagos
22878 Nigeria, (Ọja Ita Faji )

